# EKO AKEṬE.

## IWE IROHIN OSOSE.

ỌRỌ IFOJUSUN:—

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI".—W. T. STEAD.

VOL I. No. 43. SATURDAY, MAY 5, 1923. FOURPENCE.



*Editor & Proprietor*:—
ADEOYE DENIGA,
*Office*: 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.



ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.



N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.

J. F. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode laiku, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street*,) EKO





Awọn Oyinbo Onişowo yi nranşẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹşẹ ni owo to rọju a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati şe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranşẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

Awọn Oyinbo yi nşe orişirişi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranşẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja Abọmafọ ati orişirişi ọja

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

## LAGOS STEVEDORING COMPANY.

**ALL STEVEDORING WORK**

undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

**GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.**

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

*PRICES ON APPLICATION*

TO

**S. I. M. Johnson,**
9, Scale Square,
Phone 227 Lagos,
P.O. Box 498

---

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikole fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

---

## ỌGBẸNI DURO. THOMAS.

ONIṢOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni *374*. *Number* fifi-erọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

---

## Ẹ WA RA ỌPỌ ỌJA

Ọgbẹni D. B. OṢUNTOLU, onişowo Ọlanrewaju ni ọpọlọpọ ọja fun tita ni Ṣabu rẹ ni
No. 44 Balogun Street, l'Eko.

Ninu awọn ọja rẹ ni iwọnyi:— Ikoko taba, Carpets Panu ikọle, Aṣọ oniruru, Itẹkọ, Baranjẹ, Olowonyọ, Yọmini, (*Satten*.)

Ati orişirişi nkan atata miran, Ọja Ọgbẹni yi rọju o si lere ninu, ọpọku-ọyọku ni.

Ẹ lọ ra ti nyin nibẹ.

---

WHAT IS MORE REFRESHING than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads, (new arrivals from Germany.) hand and Treadle-sewing machines "Gritzner" is just to hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.

---

## KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN!

ASỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.
ASỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati
MASINI-A-NJUWON
Ọgbẹni DURO THOMAS.

Onişowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèrè onidẹ to ṣẹṣẹ de fun u pẹlu awọn MAṢINI iranṣọ ti a npe ni *Gritzner* ti ọlọwọ ati ti ẹlẹsẹ, lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Mãse leti ita Faji, l'Eko.

Ifa mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwọn nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na si "ka 'yin" to.

Ẹ lọ ba Àwúre nyin pade nibẹ.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

AJẸ NKE OKUNRUN KO PARADA O LOWO ẸBỌ NILE?

Ile Ẹjọ awọn *Jury* ṣi lọtunla ni agogo mẹsan arọ; a tanma pe awọn ti a fi Iwe pe lati wa josin f' ọba ko ni joye Apẹlẹhin ma ṣe mẹlẹ ni aro *Monday* na bi bẹkọ £25 nro nwọn lati san si Apo Ọba "ni ba jaba."

ỌGA ỌLỌPA B' ONILE NLE.

Ọran Ọga Ọlọpa kan ti o njẹ A. W. R. Awojọdu ti a sọ pe o fi aṣọ Ọba to wọ jaba nipa mimu wundia kan ti oruko rẹ njẹ Sarinatu Agbaje to si ba rojọ awuruju eyiti o bolẹ si ni Kotu awọn Ọlọpa ni ọjọ diẹ sẹhin, ṣe kuro ni ṣereṣere, gẹgẹ bi a ti ri ọran na si, lilọ ni yio kẹhin "bọyi" ni ti Ọga Ọlọpa na yio jẹ laipẹ yi.

YESUFU IKANDU ỌRUN RE.

A ba awọn iyekan Alagba Yesufu Ikandu kẹdun Iku Ọgbẹni na to ṣẹlẹ ni le rẹ ni Ita Igunnu ni ọjọ *Thursday* Ọsẹ tokọja. Ni igba aiye rẹ Oniṣọna-kan pataki ni Ọgbẹni na, o si ti ṣiṣẹ Ọgọrọ ọna fun pupọ ninu awọn Ọba ilẹ yi ati ti Ilu Oke titi o fi de Bida; ṣaṣa si ni Ọmọde moṣọ to mọ Ẹṣin igun to o.

*DR.* AKIWANDE SAVAGE. ONIGEGE-JONI JONI.

A gbọ pe *Dr.* Akinwande Savage yio bẹrẹ si ṣe Iwe Irohin Ọsọsẹ ti a o ma pe ni *Nigerian Spectator* itumọ rẹ ni Oworan ara *Nigeria* ni ọjọ diẹ si.

MALU TI KO NI'RU, ỌLỌRUN NI NLE EṢINṢIN FUN U.

Awọn ti o nka Iwe-irohin ofin *Nigerian Law Journal* oṣoṣu ti oṣu April to kọja ti *Lawyer* Adebẹṣin Fọlarin nṣe, yio ri ka-si-nkan esi to fi si iwe ti *Lawyer* E. J. Alex Taylor kọ si i ti a si tẹ sinu Iwe-irohin oṣoṣu na ti oṣu *March* to kọja nipa ti Ọrọ-ijare Ọgbẹni oniṣowo, Ezekiel Oludemi. Ọkunrin jẹjẹ ab'ija kunkun, ẹniti awọn S. Thomas & Co., Oniṣowo ni ilẹ yi ba ṣe ẹjọ nijelo lati gbe e ju sẹwọn pe o da iwe iṣiro wọn ru.

Nitotọ Adajọ Vander Meulen dẹbi ọdun mẹrin fun Ọgbẹni Oludemi nijelo nigbati nwọn ro ẹjọ na ni Kotu Abẹokuta, ṣugbọn nigbati ọgbẹni na gbe ẹjọ na lọ si "Kotu" *Appeal* (Onidajọ Mẹta) nibi, ọgafa awọn Oguñna gbongbo ninu ofin wọnyi bi idajọ ekini wo lẹhin igbati nwọn ti fi suru ọpọlọpọ gbọ ẹsun na, nwọn si da are fun Ọgbẹni Oludemi. Bayi ni Ọgbẹni na bọ lọwọ iya nla ti iba jẹ lasanlasan fun ọdun mẹrin gbako.

A tanma lati bẹrẹ si tẹ esi na ni ede wa, ninu Iwe-irohin yi ti ọsẹ to mbọ fun anfani awọn to ti bẹ wa ni iṣẹ na.

O KAN AGBAGBA, O KAN ARẸ.

Ari Iwe gba lọdọ Alagba kan ninu Ijọ ti *Catholic* (Aguda) ni Ilẹ yi nipa *Bishop* koṣe *Bishop* ti o ti di iyọrọ ti o bo Eleti Ọfẹ nisisiyi: o dun ni pupọ pe ọwọ ko tete ba iwe na lọsẹ tite sinu iwe-Irohin wa lọsẹ yi. A fi tite rẹ si ọsẹ to nbọ lagbara Baba: ṣugbọn gẹgẹbi o ti jẹ pe bakanna ni ọrọ Ọlọgbọn, nri ti aṣiwere lo nyato, a tanma pe awọn ọrẹ wa ti o ka Iwe Ọgbẹni J. K. Coker ti a tẹ sinu Iwe yi lọsẹ yi, yio tubọ ri imọlẹ ọrọ ti awa ati Eleti Ọfẹ ti njiyan si lati ẹnu ọsẹ diẹ sẹhin wa kedere.

Ni ọsẹ to nbọ kanna a o da Eleti Ọfẹ lohun Alọ to pa sinu Iwe-irohin rẹ ti ọsẹ yi to npe ni nkan-gunmọ: ohun ṣeṣẹrẹ lo sa njọ olùṣẹ loju.

## Correspondence.

Lagos, 28th April, 1923.

To the Editor, "Eko Akete."

Dear Mr. Editor,

In glancing through the interesting pages of "The News of the World," issued on the 25th March last, I was shocked with a remarkable observation of "42 years in gaol and "Black record of a persistent and dangerous criminal" which is reproduced as follows:—

"From the age of 15, Arthur Ward, 63, described as a painter, has been a frequenter, of prisons. His black record was revealed at London Sessions when he pleaded guilty to burglary at the house of Mr. Frank Hobbs, dentist, of Upper Richmond-road. He was convicted of being an habitual criminal. Ward's previous sentences were as follows:—

1875—Three months for stealing a till.

1876—Eighteen months hard labour for burglary.

1879—Seven years penal servitude for burglary.

1888—Fifteen years penal servitude for shooting at two police officers in order to evade arrest.

1900—Three years for burglary.

1908—Four years for housebreaking.

1911—Twentyone months for housebreaking.

1915—Ten years penal servitude for wounding with intent to kill.

"Sergt. Muller stated that Ward, who was described as a very violent and dangerous man, was released from gaol on licence on August 31, 1922. His sentence would not expire until 1925. There was no doubt that since he regained his freedom he had been persistently leading a life of crime.

Mr. Allan James Lawrie ordered Ward three years penal servitude and 5 years preventive detention."

With most sympathetic view of the foregoing, I venture to conjecture that this series of imprisonment, is, undoubtedly, a miraculous coincidence with that of our notorious existence seeker—the Ikoyi—Yaba Contractor-in-Chief, who has deliberately baffled the most intelligent in this community. It may be probable that the star under which they were born to the world, synchronizes with each other; because they have served almost the same number of years and our man is on the verge of commencing another term of prevention. May repentance be his future watchword.

Thanking you for space allowed.

Yours faithfully,
HAMMER.

---

*May 2nd 1923.*

The Editor, "Eko Akete"
Lagos.

Dear Sir,

With reference to the announcement in the *Nigerian Pioneer* of the 27th April last, reporting the death in England of Mr. Spencer Savage, a cablegram has been received today from the Bank of British West Africa Ltd., London, a text of which appears hereunder, in reply to an enquiry directed by the family to this Bank.

"Spencer Savage is in London to-day quite well."
*London 1. 5. 23.*

Yours truly,
DADA ADESHIGBIN.

SPENCER SAVAGE.

"As we go to press news of the death in England of Mr. Spencer Savage has been received. By his death Mr. Savage and family have been thrown into double mourning."

(*Nigerian Pioneer* 27/4/1923.)

---

*COPY.* Agege, 27/4/23.

To the Editor "Eleti Ọfẹ."
Lagos.

Mo ki ọ ku iṣẹ iwe ti o ntẹ, ti o ntuka fun mimọ ati ẹkọ enia dudu. Nwọn fi iwe ti o ṣe ni Wednesday, April 25, 1923 han mi lana, papa ọrọ ti o kọ nipa ti Superintendent ti o jẹ Biṣọp Ijọ enia dudu, nko ri iwe EKO AKETE ka lati m ohun ti o sọ nidi ọran yi. Ṣugbọn gbolohun k rin mi ni eginni, eyiti o sọ nipari iwe na pe "a o ri si Biṣọp ṣerçṣere o." Bi akọwe Ijọ enia du mo ro pe, o yẹ ki nsọ fun ọ pe, Superintenden o jẹ "Biṣọp ti Ijọ enia dudu ki iṣe Biṣọp ṣereṣ ki nsi la a fun ọ, ki o le tẹ ẹ sinu iwe rẹ, ki na le ye awọn ti iwe rẹ le si lọna.

Gbogbo awọn ti a fi jẹ Superintendent ti Ijọ enia dudu ni a fi jẹ *Presbiter Bishop* tabi Bişọp ti inu Bibeli, bi ẹnikẹni ba pe wọn ni Bişọp, ko şi wọn pe; Bişọp wọn ki işe şereşere, ti inu Bibeli ni, Jesu Kristi to da Ijọ Kristiani silẹ ko to oye kankan fun Ijọ na titi o fi lọ si ọrun, bẹni ko mu oye ti Ijọ Ju wa sinu Ijọ Kristiani.

O fi işẹ yi silẹ fun Ijọ nipa idari Ẹmi Mimọ gẹgẹ bi ede ati aşa işelu tabi ijoye ilu olukaluku Onigbagbọ. Kete ti O lọ sọrun, ipo oye ti Onigbagbọ ko to, ni Deakoni nitori ikunsinu to wa li arin Ijọ ni sa na, A ko şe Isin kan pataki fun yiyan si ipo yi, Ijọ lo yan wọn si ipo na, bẹni ninu Testamenti Titun, a ri pe oye Prebister ati Bişọp jẹ ọkanna, enia Ijọ to da oye na silẹ, ti nwọn si nyan enia sinu ipo oye na, oye meji pere lo wa ninu Bibeli,¹ oye Deakoni ati oye Prebister tabi Elder ti a tun npe ni Episcopus tabi Bishop. Oye ẹkẹta ko si. Ọkan ninu awọn oloye Presbiter ti a npe ni Bishop ni a fi nşe President tabi Alaga ibikini ninu awọn ọgba rẹ.

Ọrọ ti a tumọ si Bishop jẹ ọrọ Greek-*Episcopus*, ko si ọrọ miran ninu Testamenti Titun ti a tumọ si Bishop, itumọ Episcopus ni, Overseer (*Alabojuto*) tabi Superintendent (*Alabojuto*), ibi marun ni a lo ọrọ yi ninu Bibeli—1 Peter 2. 25, 1 Tim. 3. 1-2, Acts 20. 28, Phillipi 1. 1, Titu 1. 7. Gẹgẹbi a ti pe Episcopus tabi Bishop ni Alabojuto, bẹ gẹgẹ ni a pe Presbiter ni Alabojuto. Ipo Alabojuto ni awọn mejeji wa, ipo ikan ko ga ju ekeji. Işẹ kanna ni awọn mejeji nşe, nwọn nfi ni joye, comfirm, baptize, marry, preach, absolve ati işẹ miran titi de ọgọrun ọdun keji ti Ijọ Kristiani. Ni ọgọrun ọdun keji yi ni awọn Bishop tabi Episcopus bẹrẹ si sọ gbogbo işẹ ti tawọn ti Presbiter nşe di tiwọn nikan, eyi mu iyọnu pupọ wa, awọn Presbiter ko gba, ninu gbogbo church ni awọn Alufa Presbiter ngbogun ti wiwa mọra işe wọnyi, awọn Alufa ni ibi pupọ si ti gba işẹ wọnyi pada, iyannisọtọ, baptisi, igbeyawo ati ifi ẹşẹ jini. Ni Ijọ Alexandra fun ọdun pupọ lo jẹ pe awọn Presbiter lo nfi awọn Bishop jẹ, ninu ọgọrun ọdun keji yi ni awọn Bishop fi kelẹkẹlẹ gba ipo ati işẹ lọwọ Presbiter, ti ninu wọn wa di Prelate tabi alaşẹ pataki. Iru oye alaşẹ pataki yi ni Bishop Anglican ati Amerika ati ti Romu, iru ipo Bishop yi yatọ patapata si ti inu Testament Titun. Ilu lo sọ wọn di orişa alagbara ati alaşẹ iru eyiti nwọn nlo loni yi, a si ti nri ọla ati ipo wọn, ẹkọ ti a fi nkọni ni pe iru oye bẹ a ko le jẹ, afi ni ilu England ati Amerika ati pe Archbishop lo le fi ni jẹ oye bẹ, iru ẹkọ yi lo mu ki o sọ ni ori kini iwe rẹ yi pe "ẹnikẹni ti o ba ma gba oye Bishop ni ilẹ Nigeria yio ni lati de ilu Oyinbo gbangba Nigbati Archbishop ti Canterbury tabi Pope ba si gbe ọwọ le iru enia bẹ lori ti awọn University ti Durham ba si fi oye D.D. ta a lọrẹ nigbana ni awa to mọ iru enia bẹ ni Bishop."

Ko si ẹnikan to ba fẹ jẹ *Bishop* onipo nla yi ati alagbara ti ko ma de ilu oyinbo. Ipo nla yi yatọ si ipo ti *Bishop* inu Bibeli; *Bishop* inu Bibeli jẹ *Presbiter Bishop*, (*overseer*) ekini ninu awọn alufa (*Presbiter*) ẹgbẹ rẹ Timothy ko de ilu Oyinbo ko to jẹ tirẹ, ko jẹ oye *Arch-bishop* ko to ma fi enia jẹ *Bishop* Paul ko jẹ oye *Arch-bishop* ko to ma fi enia jẹ oye *Bishop* tabi *Presbiter*. Ki işe ninu Bibeli nikan ni alufa *Presbiter* ti a kọ pe ni *Bishop* nfi enia jẹ *Bishop* tabi Alufa; bẹni nwọn ti nşe ni atijọ, awọn Alufa (*Presbiter*) ti Alexandria ni ima fi Bishop wọn jẹ oye fun ara wọn li aisi ọwọ Bishop kankan ninu rẹ. Martin Luther lo fi Bishop kini ti awọn Lutherian Germans jẹ oye; Rev. John Wesley ati awọn Alufa ẹgbẹ rẹ lo fi Dr. Coker jẹ Bishop ni Amerika. Orişirişi ọna ni wọn nlo lati fini jẹ oye lati igba lailai titi di oni, gbogbo rẹ lo tọna, lo si fi idi oye mulẹ.

Gbogbo awọn *Bishop* wọnyi ti Alufa fi jẹ li aisi *Bishop* ninu wọn li a ka si *Bishop* atata, ninu wọn lo di olokiki *Bishop* Amerika. Awọn Alufa marun lo kọ fi *Bishop* ti A. M. E. *Church* jẹ ni Amerika, ọkan ninu *Bishop* wọn lo wa fi ologbe Revd. Tela Adebiyi jẹ oye Alufa nibi. Ko di igbati a ba de ilu Oyinbo ki a to jẹ *Bishop* awọn Alufa tabi Ijọ a ma fi *Bishop* jẹ, awọn Alufa ti wa ko şişe lati fi ti wa jẹ, bi *Bishop* awọn Amerika ti Alufa fi jẹ ti jẹ olokiki, bẹni tiwa jẹ olokiki Gbogbo awon ti a npe ni *Superintendent* bi Revs. Supts. D. A. Hughes, G. A. Oke, J. A. Lakeru J. S. Williams, J. D. Fasoro ati Ogunbiyi ni Ijọ Enia Dudu ti a fi jẹ oye lati ma fi enia joye Alufa, gbogbo wọn ni a fi joye *Presbiter Bishop* tabi *Bishop* ti inu Bibeli, a ko fi wọn jẹ *prelatical* tabi *historical Bishop* ti Gẹsi, Rome ati Amẹrika.

*Bishop* ti inu Bibeli ki işe şereşere o.

Gbọ bi Oyinbo kan Dr. Holland King, (*Professor of Divinity at Oxford*) ti wi "Lati fi oke le pe ipo *Bishop* yatọ si ipo Alufa (*presbiter*) tabi pe o tayo, irọ nlanla ni, o lodi si iwe Mimọ (Bibeli) o lodi si awọn Baba-Nla, o lodi si ẹko Ijọ England, o lodi si awọn ẹlẹkọ papa. *Bishop* Ijọ Enia Dudu ki işe "*Bishop* şereşere o"

Mo dupẹ aye ti o fun mi lati tẹ iwe yi.

Emi ni

JACOB K. COKER,

*Secretary General Committee, African Church.*

[Gẹgẹ bi ẹniti o kọwe yi ti jẹ Oloye kan pataki ninu Ijọ Africa ni a şe gba laye titẹ Iwe yi, eyiti a ti sọ pe a fi opin si ninu Iwe wa ti ọsẹ to kọja—ED—E. A.]

## EKO AKETE:

Eko, Saturday, May 5, 1923.

### TEMI ŞA! TIRẸ ŞA.!!

Ko si ohun ti o nmu ilu rẹhin ninu gbogbo nkan ju iwa Temi şa! Tirẹ şa!! ti o wa lọwọ awọn ara ilu lọ. Ti a ba şakiyesi ọrọ yi finni-finni, a o ri i pe ohun ti a jọ nsowọ pọ şe ju ni ika (*Wickedness*): bi enia meji ba jumọ fi ohun şọkan lati ma şişẹ, tabi òwò kan pọ, ti o ba şe si i diẹ bi iwọn ọdun kan tabi meji ti nwọn ti wa lẹnu rẹ, lojiji ni a o gbọ pe nwọn ti ja "aja-tuka bi ti agba-arin."

A ko ni asapẹ fun ohun rere kan bikoşe ohun buburu; jẹ ki ẹnikan şeşi şi-itẹ, nipa bibọ sinu pakute Ọba, ki a fẹ ba oluwarẹ rojọ ẹwọn wiwọ, nigbana ni ẹ o ri ainiye awọn alayọnusọ, ti nwọn yio joye "bisi-beke" "alatojubọ" ti nwọn yio ma kù sile kù sode lati tubọ lẹdi irufẹ ẹni bẹ: nigbayi ni a o ma gbọ oniruru "ma-sọ-ndoki" ọrọ wọnyi, "Ọwọ tẹ ara 'le rẹ wayi. Galegale rẹ pọju" kini şe? On nikan lo kuku wa nilu" ati awọn ọrọ "kobakungbe" miran.

Ohun ti o tun jẹ alebu miran ni pe bi a ba pe ipade kan, ibaşe nipa ọrọ ilu, tabi ti *Church*, tabi ti ẹgbẹ lasan miran, ti Ipade na ko ba gba imọran ti ọkan ninu wọn ba muwa, boya irufẹ imọran bẹ ki yio şe Ipade na ni rere kan, ti a si la a ye ẹniti o mu imọran na wa bayi, o di pe ki onimọran na ti a ko ri si imọran rẹ yi di karewa si Ipade na, ki o si ma wa ibi awọn *member* Ajọ na: Ẹwẹ, boya ọmọde kan lo si mu imọran kan wa to "tọ suna" şugbọn kaka ki awọn agba ipade na gba a nitoripe o dara, Agbẹdọ; şişa ni nwọn ma şa a ti, nitoripe irufẹ ọrọ iyebiye bẹ ti ọdọ ọmọde wa, ti ki nşe ọdọ wọn!!! ni akoko yi ni iwọ yio ma gbọ ọrọ bayi "igberaga ọmọ na rekọja ti Ẹgun kekere to nki baba rẹ ni "Ọku": "ki o rọra o, la-mọmọ ti nm'egbo ojugun." "Awọn ọgan diẹ to mọ'we"!!!

Bi a ba wa a lọ, wa a bọ, ẹmi Temi şa! Tirẹ şa!! lo nbẹ nibẹ. A! ọpọlọpọ ohun ribi-ribi melo la ti paloku larin wa ni ilẹ yi nipa iwa yi—iwa anikan-jọpọn?

Gẹgẹbi aiye ti nlọ ti a si ntọ ọ, o yẹ fun ni gidigidi lati mu iru ẹmi bayi kuro larin wa: ki a si ma şe afarawe awọn arakunrin ati arabirin wa, awọn oyinbo, fun iwa işọkan, irẹpọ ati isowọpọ ti a nri nigba-gbogbo larin wọn fun ohunkohun ti nwọn ba dawọle lati şe. A-ki-igbọn-tan.

### OTITỌ KORO.

Gẹgẹ bi ati sọ pe ki wọn fi ẹsọ şe ko ma ba di ariwo atiri ayipada nla larin awọn Ọmọ kekeke tia sọ pe wọn nşe iyọnu nipa ilu ati ebu buburu.

A gbọ pe ede tia lo ninu iwe ti ẹsẹ to kọja na ku diẹ koto loju awọn agbalagba Idumagbo bi eyi ba ri bẹ ki wọn dariji wa nitoripe ibinu ko ni ẹsẹ nilẹ Otitọ koro. AKIRIMANU.

## The Brotherhood Christian Church

### Annual Election

### 1923—24.

Executive and Outer Circle.

*Parochial——Committee.*

*President*—Pastor. A. Adedeji Işọla.

A. Ibaru Esq. Şoyẹmi Esq. A. Ọkọya Esq, A. A. Tuakley Lawson Esq, A. Şolankẹ Esq, T. A. Phillips Esq.

*Hon. Treasurer*—I. E. Abraham Esq.

D. A. Adesanya Esq, F. Faşeyi Esq, A. I. Cole Esq, J. R. Turton Esq, A. Ọla. Ajibade Esq,

*Financial Officers Auditors.*

A. Ibaru Esq, Şoyẹmi Esq, E. A. Adegun Esq,

*Sick Visitors.*

E. A, Banjoko, C. P. Cole, D. O. Thomas T, B. Ojọ, Esq.

Drummers.

A. Ọla. Ajibade Esq, *Drum Major.*

*Drummers*—I. A. Dosunmu Esq, I. Fafunwa Esq. Eşubi Esq. T. B. Ojo Esq. H. O. Isikalu Esq.

Choir.

Vacant—*Organist and Choir-master.*

Master Bababunmi *Asst: Organist.*

Sunday School.

| | |
|---|---|
| *Superintendent* | Pastor. A. Adedeji Işọla |
| *Manager* | S. A. Coleman Daniel |
| *Asst. Manager* | A. Ọkọya, |
| *Hon. Secretary* | F. Faşeyi |

Wardens.

G. B. Pearse Esq, A Oni-Orisan Esq. J. A. Davies, Esq. B. George, Esq, S. A. Coleman-Daniel, Esq, P. P. John, Esq, J. I. Salakọ, Esq, A. I. Cole, Esq.

# SINGER! SINGER!! SINGER!!!




Kinla! Tiwa ki nẹe a nṣẹṣẹ wa onibara, kini a ti nṣ'oku l'ọrun, nwọn pọ to wọbu larin orişirişi enia jakejado Nigeria.

Ẹrọ iranṣọ "SINGER" kọkan, ni gasikia polowo ara rẹ.

Pataki ohun ti o mu 'Ẹlẹha jade ọsan' ni wipe a nfẹ mu wa si akiyesi awọn ogunlọgọ onibara wa

TI EDINWO NLANLA TI A ŞE

ninu owo ẸRỌ IRANŞỌ wa ati IRIN-IŞẸ wọn, eyiti o fẹrẹ ba iye owo ti a nta wọn ki ogun Jamani to bẹrẹ nijelo mu.

wọnyi ni diẹ ninu awọn ohun pataki ti o jẹ ki ẸRỌ IRANŞỌ SINGER t'idi awọn ẹrọ iranṣọ miran b'omigbona.

Ikinni.—Ẹwa, itẹju ati idakẹ rọrọ l'ẹnu işẹ.

Ikeji.—Irọrun ti o wa lati ri orişirişi irin işẹ rẹ ti o ba bajẹ ra.

Ikẹta.—Ifọwọsọ'ya lati tun gbogbo Ẹrọ Iranṣọ 'SINGER' şe nigbakugba l'ọfẹ ibaşepẹ a ra lọdọ wa tabi ni Ẹka-ile ọja wa miran.

Wa bere iye owo wọn ni Ile-ọja wa ni Popo nla l'eko nibiti 'Ẹrọ Oyibiri' nl'agogo.

Phone L222, Extensions 2 & 3.
P.O. Box 171.

DADA ADESHIGBIN & SONS,
*Sole Importers Singer Sewing Machines.*


---


ỌGBẸNI OYINBO ONIŞOWO

***R. S. JAMESON***

Ti Opopo-Nla

Ni Iyọ to funfun bi Lekeleke fun tita ninu Apo ogoji Iwọn, £5 10 o lo nta a fun *ton* kọkan

Ọrẹ, lọ sibẹ, maşe jẹ ọbẹ obu o!


**To whom it may Concern.**

The Public is hereby notified that Mr. B. O. JOSEPH of 64, Breadfruit Street, who had wanted to Raffle his Motor Car has decided not to do so again and has instructed his Driver who carries the list about to refund money to those who have paid.

Lagos, 13th April, 1923.

## WANTED.

Reliable Agents required for sale of English Ready-made COFFINS, at Lagos Abẹokuta, Ibadan and Jẹbu-Ode.
For Terms and Conditions,

Apply to A. BANK. ANTHONY,
137, Tokunbọ Street, Lagos.

## A TOTO, O!

A nfẹ Enia "GIRIKI" ti yio ṣe oju Ọgbẹni A. BANK ANTHONY ni Eko, Abẹokuta, Ibadan, tabi Jẹbu-Ode, lati ma a ta awọn POSI-meremere, ti o ti i'u Ọba wa tun Ọgbẹni Oniṣowo na.

Ẹniti o ba nfẹ, ki o kọwe si Ọgbẹni na. ni adugbo rẹ 137 Ita Tokunbọ l'Eko.

## Sorinolu's Grammar School.

*(The first ever Established in Abeokuta and Ijẹbu-Ode since 17 years ago.)*

All Grammar School Lesson efficiently taught to Advantage and Success.

*Tuition Fess Rated by the Readers :—*

Primers I and II—3/- *per Quarter.*
Readers I to III—3/- *per Quarter.*
Readers IV and V—6/- *per Quarter.*
Classes I to III—9/- *per Quater.*
Boarding Fee—£1 2s 6d. Monthly.

This is beside the Tuition Fee ; and includes Lodging, Cloth-Washing, and Cooking Services.

PLEASE NOTE!

Payments strictly in advance ; otherwise the Pupil shall suffer a temporary cessation from School and Boarding.

For futher particulars apply to

ARIYỌ ṢORINOLU,
*Principal & Proprietor.*
Iporo Ake, Abẹokuta,

## ILE OWO-ỌJA RIRANṢẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

Ọgbẹni S. B. VINTURA, Aṣoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranṣẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Ṣẹda, Onini, Owu-Ṣẹda alarabara, Ohun-elo awọn Aranṣọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ *(Felt)* Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni tita ti owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' o kọjusi Kọtu, l' Eko.


## IGBẸ L' OWO WÀ.

EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-òwò wọnyi ti gba Ọja *(Produce)* l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)
G. B. Ollivant,
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)
MacIver, African
Association, John Holt, Miller Bros.
£13 10 fun *ton* kan

EPO.

£24 10 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

COCOA.

Lati £27, de £28, fun *ton* kan bakanna


## WANTED.

A good COOK capable of preparing all kinds of Native "Chops."
Good wages to a suitable man.
Apply to the Editor of this Paper.

## All for Bicycles and Motors.

Ask for KADUNA STORE,
No. 81, Ọdunfa Street,
Near the Famous Building of
Mr. Andrew Thomas, Lagos.

*At reduced prices*

Special Dunlop Bicycles Tyres Beaded-edge 12/-
do. do. 15/-

The above Tyres are specially for Rudge-withworth and German Cycles and we have complete workshop for repairing of all kinds of machinery. Send all your repairs' Bicycles, Motors, Sewing machines, Gramophone, painting, enamelling work soldering, etc., to the Properitor at the undermentioned address. All Bicycles spare parts on sale.

SAM. A. CLAY,
No. 1 Macauley Street,
or at Workshop, 81, Ọdunfa St.
Lagos.

*Telegram Address*:—KADUNA STORE,
81, Ọdunfa Street,
Lagos.



## IYA AFIN SABINA BỌLAJOKO

Ti No. 39, Ita Matinin jẹ ẹniti o gbaṣẹ ati ... ta orişirişi ỌTI o si nta awọn nkan

Ipanu ni Ṣabu rẹ yi.

... lọ ke si i, Wara-ṣeṣa ni ọja rẹ, owo wọ... si mọ-ni-wọu ti makunn...



## *The Philharmonic Band.*



Awọn oni fere yi nfun pẹtẹ, ilù nwọn si dun bi oyin l' eti.

Owo ti a nfi pe nwọn ko pọ, nwọn ko si kọ lati lọ si ilu ki ilu.

Ẹni ba fẹ nwọn, ko kọ iwe si,

*THE SECRETARY.*
c/o Aáfani Motors
The Marina Lagos.



"KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,
119, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

MRS. FRANCES ADEYEMI THORPE (NEE GREEN) K'ọgeniwẹ, a fi iṣẹ ni lapa ṣe fuja, bẹrẹ si Iṣẹ Ọna rẹ ni No. 119 Tokunbọ Street. Ni ti aṣọ riran ni aṣa orişirişi ko ni ẹgbẹ.

Ẹyin ọmọge ti nfẹ iṣẹ kọ, Ẹ lọ ri i.

---

### DRESS-MAKING.

"KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,
119, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

If you want a perfect fit and artistically made dress, patronize the above institute and you will be amply satisfied.

Girls requiring tuition in the modern and up to date style of Dress-making please apply to the above Institute.

*TERMS MODERATE.*



## "O ṢE' WỌ NI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ lọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.

Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

( MORNING )

Masses Isin Arọ.

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

( EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S ( Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi. |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | St. John's ( Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. & 4 p.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. | Holy Trinity ( Ebute Ero.) | Rev. S. J. Gansallo |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev J. A. Leigh |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | do. | Rev. A. N. Cole |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | do. | Rev. S. A. Pearce |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | do. |
| 7 p.m. | | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | | Bro. E. Adeniyi Oluwa |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. Pres. Bp. G. A. Oke |
| 7 p.m. | | Rev. J. F. Ogunko |
| 9 a.m. | Erelu | Bro. J. H. Lawson |
| 7 p.m. | do. | Bro. Ignatius Martins |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. E. A. Akinola |
| 6.30 p.m. | | Rev. H. T. King |
| 9 a.m. | Zion | Rev. N. J. D. Ṣomuji |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. E. A. Williams |
| 4.30 p.m. | | Bro. L. A. Randle |
| 9 a.m. | Ararọmi ( Baptist ) | Bro. E. A. Ojo |
| 4 p.m. | | Rev. A. A. Puddicombe |

**FIRST BAPTIST CHURCH**

| | |
|---|---|
| 10.30 a.m. | Bro. S. M. Phillips |
| 6.30 p.m. | Rev. J. K. Williams |

**EBENEZER (BAPTIST)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Rev. E. C. Alabi |
| 6.30 p.m. | Bro. S. M. Phillips |

**BROTHERHOOD**

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m. Ilupesi | Bro. J. R. Turton |
| 7 p.m. | Pastor A. Adedeji Iṣọla |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Bro. Thomas Akajagbo

**AHMADIA (ISLAM)**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde

5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajọṣe ( Bamgboṣe Street. )

**COLONIAL CHURCH (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion

6.45 p.m.—Evensong and Sermon Rev. H. A. Lewis

**SALVATION ARMY.**

Services at Glover Memorial Hall, 10 a.m. an[d] in the Streets.

---


SIMENTI NYAJU!!!

Ọgbẹni Mumuni Ainde ti No. 27, Ita Masse[y] L' Eko ni ojulowo *BIRIKI* fun tita fun ẹnikẹ[ni] owo wọn si rọju.

Ẹnikẹni to ba nfẹ ba Ọgbẹni na ra awọn *BIRIK[I]* yi le lọ ke si i ni adugbo rẹ.

Ki a ri nyin o, Ẹnikeji, Ijafara lewu.

---

W' O BI, ẸNIKEJI, OJU L'ỌRỌ WÀ!!

Maṣini Aranṣọ ti a npe ni "MUNDLOS" wa fun tita niti Ọgbẹni J. S. JOHNSO[N] ti 16, Ita ọja Ajaṣẹ, ati ni Ṣabu A[...] MASU ni Ita Agarawu ni owo ọpọku-ọ[...]

---

Ni Ile-iwo oriṣiriṣi ọja ti [...]na Ọgbẹni ARNOLD SCHLESINGER, Oniṣowo ara Jamani ni Ita 7, Labinjọ, leti Ita William

lẹ gbe le ri awọn ẹrọ RECORDS ohun [...] ijọ to ṣẹṣẹ de ra ati awọn Ẹrọ wọny[i]

Ẹrọ ohun-orin GRAMOPHONE

Kẹkẹ-olo-gere BICYCLE

Awo Abọmafọ ENAMELWARES

Waji BLUE ati ogunlọgọ ọja mira[n]

E sure tete lọ ra ti nyin nibẹ.

MESSRS. J. R. THOMAS & SONS of Lisabi Hotel, Itori, beg to inform the public in general that they have been licensed by the Nigerian Railway to sell and serve refreshments etc. etc. to all passengers travelling on trains on up and down journey at Itori and Olokemeji Stations at very moderate prices. This venture has already been opened by them to the public at the aforesaid Stations any one travelling up to Ibadan and back, and needing supply of any kind of refreshment should intimate us through the Station Masters Iddo to Ibandan, and *vice versa*.

---

"EKO AKETE."

A le ri Iwe-Irohin yi ra lọdọ Asọjù wa.

Ajenifuja Stores, 109 Broad Street, LAGOS.

Ọgbẹni VIDAL R. COLE.

---

**WHY LOOKING SAD.?**

Are you impotent, suffering from sexual weakness, nervous postration or loss of memory why don't you use Muiracithin and get instant relief. It will rejuvenate you, and restore your youthful energy. Its effect is wonderful and permanent. No matter how Chronic your case may be. It is also unsurpassed remedy for women in case of barreness, irregular Menstruation sexual Neurasthegia etc., etc. In order that every sufferer should have a trial of this valuable Medicine, the prices are reduced for only limited time at 4/6 in bottle of 50 pills, and 6/6 in bottle of 100 pills obtainable at "Ajenifujà" Store No. 109 & 111, Broad Street.

VIDAL R. COLE,
*Sole Agent.*

---

**FIRST CLASS TONSORIAL ARTIST**

Mr. A. L. KOSỌKỌ the well-known Barber late of Customs Street, Lagos, begs leave to inform his many clients of his new Establishment at 135, Victoria Road, this City, where prompt attendance will be accorded them as heretofore.

Razors, Combs, Perfumes, etc, are also on sale at prices to suit everybody.

Call or send; warm wellcome to all.

NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

---

AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.

---

**First Class Dressmaking!!!**

Mrs. ABRAHAM ASHARR trained in Paris, begs to offer her professional services to the public.

Latest modes at moderate charges satisfaction gauranteed. Call at once at

117, Victoria Road,
Lagos, Nigeria.

---

**PAGIDARI!**

*Olokiki* S. FRANCIS LAWANI *Saka-jojo*.

Onişowo ni Victoria Road ni wabi-wọsi ohun elo, fun Ọmoge ati Ọmọde-m'ẹṣọ ti o si nta ni ita oloko-o-gbowo.

O si tun ni aye pataki kan ninu ile ọja na, ti a nşe Gbajamọ fun ni, ni owo-ti-kotani-lara, bi şile kan, sisi, tabi tọrọ.

Egbogi orişi-rişi iwosan onirunru aisan, Ipara olo-orun, ati agbọrun Jigin-oju, ati nkan mere-mere pọ to wọbu nibẹ.

Ikan-o-jọkan irin iṣẹ ati Egbogi ti a fi nya *Photo* aworan wa nibẹ ni ọpọku yọku.

Onirù-nru wosiwosi ti a ko le ka tan pọ nibẹ bere ohun-ko-hun ti o ba nfẹ yio pese rẹ fun ọ.

O ngbero laipẹ, lati şi ile Ẹrọ Idan Awoşẹju ti a npe ni *(Cinema)* ni Great Bridge Street, Iduumagbo.

Şoroko a gbe şeranwo ni igbati o ba şi ibẹ Irohin ko to afojuba.

*P.O. Box 159* *Phone 214*

## ALASE LEATHER FACTORY.

### "ILE ALAWO."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices.




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣọwọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*:—Alawọbata, Eko.

---

### ỌBẸ L' ỌMU AGBA

A nlẹ "Kúkù" to mọ orişirişi Onjẹ Ilẹ wa ni sise. To si le jẹ ki ọbẹ ma sọ "Tapa" lori ina. To si mọ "Kọtọ" Ọbẹ di lọwọkan.

A o sanwo Oşu to rọju fun ẹniti o ba mọ işẹ yi şe.

Ẹ kọwe si Oniwe Irohin yi.

---

### AWỌN IWE ỌGBẸNI J. G. KUYẸ

Fun Ile Ẹko.

| | | |
|---|---|---|
| A. B. D. Alaworan | ... | 3d. |
| Iwe Alaworan Kini | ... | 7d. |
| Iwe Alaworan Keji | .. | 9d. |

Awọn iwe wọnyi ko ti si lode ni sa'kan nitori ogun Germani, şugbọn wọn tun de nisisiyi, a si le ri wọn ra ni Ile Iwe tita ti C.M.S. ninu ilu yi tabi lẹhin odi.

Itan ati owe ti o wa ninu iwe wọnyi dara pupọ, bẹ gẹgẹ ni awokọ inu wọn dara fun ọmọde to, ẹniti o ba dan a wo yio ri pe ọgbọn ẹniti o ti jẹ olukọ awọn ọmọde fun ọdun pupọ li a fi to awọn iwe na lẹsẹsẹ; kişe işẹ *sare nbaja*.

A le ri awọn iwe wọnyi ra pẹlu lọdọ oniwe ni ẹdin owo, 66, Ibadan Street, Ebute Mẹta.

---

### GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti nş' oku l' ọrun?
Ki la ti nş' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?

Ọpọkuyọku si ni, wa şa eyi to wu ọ ni:—
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.